COMMONWEALTH ti ÌLÚ VIRGINIA

ẸKA ÀWỌN IṢẸ́ ÀWÙJỌ
Ọ́fíìsì Komíṣọ́nà

S. Duke Storen
Komísónà

Ọjọ́ 7 Oṣù Kẹjọ, Ọdún 2026

Èyin Aláràtúntà Virginia,

Fún ẹgbẹẹgbẹ̀rún àwọn ìdílé Virginia, SNAP máa nṣe ìrànlọ́wọ́ láti fi oúnjẹ sórí tábìlí ó sì nṣe àtìlẹ́yìn ọjọ́ iwájú tí ó túbọ̀ ni ìlera, tí ó túbọ̀ ní àábò. Àwọn aláràtúntà jé abala kan pàtàkì ti isẹ àkànṣe yẹn, mo sì mọyì àjọṣepọ̀ yín tí ó ntẹ̀ síwájú bí a ṣe ti nṣe ìmúṣẹ ìyípadà pàtàkì kan sí SNAP ti Virginia.

Bẹ̀rẹ̀ láti **Ọjọ́ 1 Oṣù Kọkànlá, 2026**, àwọn ànfààní SNAP kò lè ṣe é lò láti ra **àwọn ohun mímu onígáàsì tí ó ní ṣúgà tàbí àwọn ohun amú nnkan dùn àtọwọ́dá** (títí kan sódà, sódà tí kò ní ṣúgà /òdo sódà. àti àwọn ohun mímu afúnnilágbára tí onígáàsì). Gbogbo àwọn ohun mímu ẹlẹ́rìndòdò míràn ṣì ní àmúyẹ SNAP.

Ìyípadà yìí kan **gbogbo àwọn kárà-kátà SNAP ní Virginia**, títí kan àwọn ìbéèrè fún ọjà lórí ẹ̀rọ tí o múṣẹ. Virginia nṣe àmúlò ìmúdójúìwọ̀n yìí lábẹ́ àfojúfò kan tí a fi ọwọ́ sí. ti Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ọ̀gbìn Ilẹ̀ Amẹ́ríkà (USDA). (Àfikún àlàyé nípa àfi ojú fò ni a lè rí www.fns.usda.gov/snap/waivers/foodrestriction/virginia)

Láti múra sílẹ̀ fún ìmúdójúìwọ̀n yìí:

- Ríi dájú pé **ètò ibùdó ìrajà rẹ** dí àwọn ohun mímu onígáàsì, ẹlẹ́rìndòdò tí a fi gbèndéke sí bẹ̀rẹ̀ láti Ọjọ́ 1 Oṣù Kọkànlá.
- Ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn òṣìṣẹ́ lórí àwọn ìyípadà àmúyẹ SNAP.

Láti ṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn ìmúdójúìwọ̀n ètò, a ó pèsè **àtòkọ Kóòdù Ọjà Àgbáyé (UPC) kan** ti àwọn nǹkan tí ìyípadà yìí lè ní ipa lé lórí. O lè retí ímeèlì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ láti ọ̀dọ̀wa láìpẹ́ pẹ̀lú àtòkọ yìí.

Mo fẹ́ fi dá ọ lójú pé Ẹ̀ka Àwọn Iṣẹ́ Àwùjọ ti Virginia (VDSS) wà níbí láti ṣe àtìlẹ́yìn fún ọ àti okòwò rẹ.

A ó tẹ̀ síwájú láti máa pèsè:

- Àwọn ìlànà nnkan tí ó ní gbèndéke tí ó hàn kedere
- Àwọn àwòṣe àmi àti àwọn ohun èlò oníbàára
- Ìrànlọ́wọ̌ ìmọ̀-ẹ̀rọ nípasẹ̀ ímeèli
- Àwọn ẹ̀kọ́ orí ẹ̀rọ tí kò pọn dandan pẹ̀lú àwọn ànfààní fún ọ láti béèrè àwọn ìbéèrè

Ẹ̀yin Aláràtúntà Virginia
Ọjọ́ 7 Oṣù Kẹjọ, Ọdún 2026
Ojú Ewé Kejì

Ẹ lè wá àwọn ohun èlò ìbánisọ̀rọ̀ tí ó nkọjú sí oníbàárà, àwọn àtòkọ tí ó hàn gbangba ti àwọn ohun mímu ẹlẹ́rìndòdò tí ó yẹ àti èyí tí kò yẹ, àwọn ìbéèrè tí a máa nbéèrè nígbà gbogbo àti àfikún àlàyé ní **www.dss.virginia.gov/SNAPHealthy**.

Àwọn ìbéèrè?
Gbogbo àwọn aláràtúntà tí SNAP fún ní àṣẹ ni a pè láti dara pọ̀ mọ́ àjọ wa fún àwọn ẹ̀kọ́ orí ẹ̀rọ oní wákàtí kan láti kọ́ ẹ̀kọ́ nípa SNAP Healthy àti ìyípadà sí àwọn káàdì ṣíìpu/EMV. Àwọn olùdarí VDSS yóò ṣe àfihàn lẹ́yìn náà wọn yóò pè fún àwọn ìbéèrè láti ọ̀dọ̀ a wọn aláràtúntà.
Jọ̀wọ́ dara pọ̀ mọ́ wa lórí èyíkéyìí:

- Ojóbo, Ọjọ́ 20 Oṣù Kẹjọ, Ọdún 2026, aago 2 - 3 ọ̀sán – Te ibí láti fi orúko sílè
- Ojóbo, Ọjọ́ 3 Oṣù Kẹsán, Ọdún 2026, aago 2 - 3 ọ̀sán – Te ibí láti fi orúko sílè

Ẹ ṣeun fún ìfọwọ́sowọ́pọ̀ yín láti ṣe àtìlẹ́yìn ìmúdóìwọ̀n tí ó rọrùn fún àwọn oníbàárà àti àwọn òṣìṣẹ́.

Nítòótọ́,

S. Duke Storen